AWON AK'OKO NTE NILU OYINBO



SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO



VOL. No. IX 523. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, JUNE 8, 1957. KOBO MEJI (2)

## Miss Nigeria Nilu Oyinbo



Obiarin ti a nwo ninu aworan yi ni enití nwon ri pe en l'o darajulo nile Nigeria (Miss Nigeia) or l'o mba awon omo akeko ti o lo ko ise nile Oyinbo lati ile Nigeria soro nigbati nwon ri ara won ninu ile awon British Council. Obinrin yi ni a w o n npe ni Omidan Grace Tinuke Oyelude, ojo ori re koju odun merinlelogun lo.

Awon enia meji ti arewa obinrin na mba soro ni Ogbeni J. O. Fuwa, ati L. O. Emelonye. Ohun ti o gbe omidan yi de ilu Oyinbo ni wipe, nigbati nwon pe ipe lati mo arewa ni ile Nigeria, o le ni iwon ogbaji obinrin ti o fi aworan r e ranse, sugbon, ewa ti Omidan Grace ta gbagbe won yo.

Awon Oyinbo Onisowo U. A. C. l'e omu omobinrin na kiri ilu Oyinbo. O de ibiti nwon nse keke Basikulu, o de ile ere kan, o rin lori odo Thames, o lo be Ile Hampton wo o si tun lo be agogo ti o nkorin ninu ero gbohun-gbohun wo pelu.

## OBA KOSOKO ATI OLOYE TINUBU

Awon opitan so wipe ikunsinu wa larin awon Ijoye Eko ati Oloye obinrin ti a npe ni Tinubu, nigba gbogbo ni awon omu esun re lo si odo oba Kosoko wipe, obinrin na ti a npe ni Tinubu ni aje. Kosoko ko gbagbo, sugbon awon Ijoye fi dandan le wipe, ki o wa lo bura loju Osugbo, Kosoko ko gba.

Tinubu ni eru kan ti a npe ni Seku, bi eru yi ba yi wo omi, yio di eranmi. Nigbati oro ibura yi kan si Tinubu, o ranse si Kosoko pe ki o jeki on lo bura na.

## Awon Ak'oko Nte Nilu Oyinbo

LONDON – Ni ilu Oyinbo ni a g b o wipe awon agba ijo ti a npe ni Church of England wipe enikeni ti o ba ti ko oko tabi oko ti o ba ko aya sile ti o ba tun fe gbeyawo lekeji awon ko ni gba lati se isin fun u.

Alufa ijo tio ba fe, o le lo se adura fun awon akoko wonyi ninu ile won, sugbon ko nse wipe ki won se ten ki won mu gele ki won yo ileo ki won ma gbe enu bo wa sile isin lati wa gba ibukun, eyiti won ti gba lekan ti won k o lo daradara tani ni ona eto gegebi ilana igbeyawo.

Olori ijo awon onigbagbo elelowo Bisopu Dokita Fisha ni on faramo ofin yi. Boye e t o ofin yi le mu ki awon akoko lokunrin ati lobinrin, ni f u n f u n ati ni dudu rotu pa iwa won da.

## Sardauna lo si Manchester

Alhadji Ahmadu ti o nse Sardauna Sokoto, ti o si je olori kan pataki ninu awon asiwaju ti Ogbeni Alan Lennox Boyd fe ba soro n i p a ominira ile Nigeria, de kan lo sile Manchester ni bitì awon ko ni ise meji ayafi aso hihun lati lo da Mayor ilu na lohun nitì apeje nla kan ti Mayor ilu na pe si.

Oko reluwe ni Sardauna wo lo si ilu na, nitì o si se amona re lo sibe ni Alhadji Aliyu ti o nse Oloye Makaman Bida a t i asoju i l e Hausa, Alhadji Abedu Maliki.

AKIYESI PATAKI

Iwe irohin titun t i Oruko re nje "IMOLE ti a ti nse ikede re yio bere si jade lati ojo kejila osu y i ni i l e tiwe Modupe Press.
16, Bamgbose Street Lagos.
Kobo kan pere ni, a si tun nfe asoju ti yio ma ta a kakiri agbaiye.
Kowe si Olotu
"IMOLE"
16, Bamgbose Street Lagos.



# Ijogbon Be Sile Lori Oye Mayor Enugu

ENUGU Ogbeni Gogo Abbey ti o nṣe akowe ẹgbẹ N.C.N.C. ni awọn yan lati ṣe iwadi kini ohun ti o fa ijogbon o ṣe Mayor ko ṣe Mayor ti o ẹfẹ du ruke-rudo silẹ.

Ohun ti o fa idi ruke-rudo na ni wipe dida-duro ti awọn da Ogbeni Chidozie ti o nṣe aṣoju Mayor duro fun ẹsun pe onimodaru ni ati tori on lo ṣe junoṣi ti nwọn fi ko Imoru Aitine silẹ lati yan si ipo Mayor.

Die ninu awọn igbimo yi binu fiṣẹ silẹ lasapa didaduro ti nwọn da Imoru duro. Agbọ wipe nwọn ti bẹrẹ lati wadi ododo ọrọ na ki a le mọ tani jẹbi ati awọn tani jare.

# Oro Olofa pari si wipe kafi egungun otolo to

ILORIN. Ijoba Ibilẹ Ilorin ro ọrọ so yọ Olọfa kuro loye, tabi a ko yọ ẹ kuro loye wo, nwọn si wa pari rẹ si wipe ejeki a fi egungun otolo to, a si pari ede koyede kuro. Nigbati awọn nsọrọ yi, a gbọ pe awọn ọmọ ẹgbẹ N.P.C. yera kuro wipe, awọn ko lowọ ninu ọrọ yen.

Bi ọrọ na ti lọ niyi, Ijoba Ibilẹ Ilorin paṣẹ fun ọba Olọfa wipe, kiakia ki o yera kuro lori oye ọba, nitori nwọn fẹ fi ọba miran jẹ. Awọn ọmọba, awọn ẹgbẹ Ilọsiwaju Ilu Offa, ati ẹgbẹ Afẹnifẹre tako aṣẹ na, nitoripe, o lodi si aṣa ilẹ Yoruba.

Awọn enia nwọnyi tun kowe si ijoba Oke Oya wipe, awọn nfẹ ki ijoba ṣe iwadi nipa iṣe Alikali Ilorin, ati awọn ti agbe Ilorin pẹlu. Awọn mejila kan ti o jẹ olori tabi ọga nibi iṣẹ ijoba ibilẹ wa ṣiwaju awọn enia na, nwọn ṣe ikilọ fun wọn pe ki nwọn lọ fa awọn enia wọn leti nipa ohun ti awọn nfẹ lọwọ si. Ki nwọn maṣe ni ẹnikan lara.

Ogbeni S.O.B. Okin tako awọn enia na pe nitori kini nwọn ṣe ni lati ma fi yiyọ kuro ni bi iṣẹ dẹruba awọn enia na O fi nbaa gbogbo enia pe ki nwọn maṣe feti si ihalẹ ti ijoba Ibilẹ Ilorin fi nhalẹ mọ wọn. Alikali agba dahun pe, tẹlẹ tẹlẹ ẹnikan ko lagbara lati dẹruba on, ati biko ba si ti Alikali, ko si ẹnikan o le joko ni alafia.

Ibẹni Ogbeni J.G. Ekunrin ti binu, o ni ki Alikali Agba ko ọrọ na jẹ, ipade na deru, o si nfẹ di ija, nigbana ni Ọba Ilorin da si, o ni ki nwọn so pe awọn ko wibẹ nwọn ti wibẹ.

# Owe

Nigbati ẹnintin nje Kudayisi, ẹnikan ko gbọ, ṣugbọn lojo ti Kudayisi wa jẹ ẹninti san ni ariwo fa.

**Kere o!**

A ti ni origirigi ogun German to ṣeṣe de, fun osiyuru nisan sọkun tobinrin. Tete wa ra tiyin k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.

# Oba Olowo gbategun lo silu Oyinbo



Aiye ijoun ko jọ ti isisiyi. Nigba iṣaju ni ọba kan ko gbọdọ daba lati fi ilu rẹ silẹ lọ si ilu keji, nwọn si tilẹ sọ wipe, ọba meji kogbọdọ f'oju kan ara wọn. Ṣugbọn ni aiye ọlaju ti wa isisiyi, Ọba ti o ba fẹ, le gbategun lọ sibiti o gbwuu, nitoripe awọn ọba ko nṣe ẹlẹbọ. Omiṣẹra ti de ninu aiye w'ọra ati idẹra fun gbogbo enia.

Ẹ o ri Aiaiyeluwa Ọba Olọwo ilu Ọwọ ti o gba isinmi kuro lori oye, o si gbọ'lọfẹ-ara lọ silu Oyinbo pẹlu iyawo rẹ.

Kabiyesi! ọkọ a refo o.

# Ole ngbadura oninkan ngba tire

Jagude, baba ole, wọn ngbadura, o ni Olorun jọwọ ma jẹ ki onilẹ ati alejo ji o, ti on yio fi lọ kiakia ti on yio si fi bọ kiakia. Ki a ma dalẹ mọ, ojo oke pe.

Jagude ni aja, onilẹ ni tirẹ. Aja ole ngbo, Aja onilẹ ngbo, Ariwo wa gba ilu kan. Aja Jagude paṣẹ fi ariwo si re gbalẹ. Onilẹ taji, o ni boya digbolugi ti wọ aja on lara ni, lo ba tun dubulẹ nitirẹ. Jagude, ole ti o ti da ọkẹ fun aja ba ko gbogbo ile lọ ati aja ọdẹ nibojẹ yi.



"A'W'ỌMỌLA"
Asiko ooru a maa ko inira ba ọmọ-ọwọ. A maa sọkun nitoripe ko gbadun. Jẹki o ni itẹlọrun nipa lilo

Dr. LYNN'S
CHILDREN'S
SOOTHING
MIXTURE



## Kilo le mu obinrin yi fe lati pa-ra re?

ENUGU. Agbako ori ede l obinrin kan ti nwon npe ni Ifenwani lo bimo titun, omokunrin kan gbogbo enia si nki wipe, o ku orire, ti nwon si nyo ayo omo titun na.

Kawi, kafo, nse ni iya omo titun yi, lo yo obe, o si nfe fi gba ara re lona ofen opolope wipe awon enia wa nitosi re ti awon si ba jijakadi ki nwon to gba obe na lowo re.

Pantiwa! kilo faa, iwo ti gbogbo enia mba yo ayo orire, kilo tun le mu o lati fe pa ara re ewe?,

Obinrin na dahun wipe, e jomisi o jare ase beni orun dun ju ile aiye lo! Nigbati on mbe lori ikunle ibimo, ogba alijonno ni on wa, ibe ko se fi enu juwe, ko je dudu, ko je pupa ko je ayinrin, ko si ibinu, ebi ko npa enia gbogbo gbogbo enia sa wa nibe pelu ife. Anobi Buramo wa, Yakuba, Muse, ati gbogbo awon elara mimo wa nibe ha! eyago fun mi ki nlo. Nigbehin obinrin na gba ebe lati joko toju omo re, Eyi nko?

## Isele kan ja nile awon Tatambulu

ISTANBUL. Irohin kan wa wipe lojo 26th osu May 1957, isele kan ja n ilu awon Tatambulu (Turkey) ti o je wipe, larin oru ojo Saturday si oru ojo Sunday igba metadilogun-le-lodunrun ni isele na fi mile kiji-kiji.

Ile merindiladorun-le-nirinwo lo dawo lule, enia merinlelogorin lo fi ara gbalamo.

Ni agbegbe ilu kan ti nwon npe ni Bolu odidi abule meaan lo rasa si abe ile, o si le ni adota enia to padanu emi won si abule kokan.

E Ma Ka Iwe Irohin

Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun

Ki E Si Ma Polowo Oja

Yin Sinu Re

Polowo oja re sinu iwe irohin

Eleti - Ofe

## Oba Obinrin Gesi lo be ilu Paris wo



Ilu Paris je olu ilu fun awon Faranse. A si gbo wipe iran ilu na ni wiwo tabi ariya ibe ko nsu enia orisirisi okan-kojo-okan ni iwo yio ma ri. Awon alasodun so wipe, eni ti o ba ao pe iran ilu Paris su on, o ye ki olawa re lo ku danu.

Ilu Paris yi ni Oba obinrin Gesi lo fi oju kan lsipa yi. Obinrin ti o wa ni waju ti a nwo yi ni Elizabeth keji oba ilu Gesi, oni ti o wa ni egbe otun re ni Ogbeni Coty ti o duro gegebi asiwaju gbogbo ijoba Faranse oni ti o duro lehin ogbeni Coty ni Duke ti o nse oko oba.

Aranso kan pataki ti a npe ni Normar Hartnell lo ran aso ti oba yi wo ni iru eyiti o je wipe enikan koiti wo iru re ri ni ilu Paris, lara aso na ni orisirisi dayamon gbe wa, oni dudu, pupa, oni koko ayinrin olofo funfun ati oni bulu.

Ha! ni gbogbo awon obinrin Faranse nse nigbati awon ti aso na.

# ELETI QFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
78, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23570
VOL. IX, NO. 523, LAGOS, SATURDAY JUNE 8, 1957


## Ijafara Lewu

Wo ọtun rẹ ki o si wo osi rẹ wo dara-dara ki o to sare kọja lọ loju ọna moto; nitoripe ewu pọ jọjọ ni sisoda ọna moto. Eyi ni a fi se wọ'kan wa ti oṣẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa, papaa ẹnyin ti o ngbe awọn ilu nla nla bi Eko, Ibadan ati awọn ilu bawonsi.

Nigbiyi lojojumọ ni ẹrọ moto nde lati ilu awọn oyin'o, bẹni oju ọna moto, ko gboro ju bi o ti wa lọ. Bawo ni ao ti se e? Ko si ohun meji ti a le se ayafi ki a kuo fun adura, ki Ọlọrun le fi iṣọ rẹ sọ wa gagbọn ki awa paapa maṣe gbagbe lati la oju wa kedere lati wo ọtun ati osi daradara ki a to sare kọja loju ọna moto.

Eyi ni imọran ti a le mu wa fun nyin lọsẹ yi nitori aiye ti di aiye ologare, akoko ati igba ase lo asure tete. Iku di meji epini bẹni ẹmi ko pe meji. Ijafara l'ewu.

---



### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ni orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma nba omode ja ni asiko enin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun ọmọ won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)

O wa lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

19, VICTORIA STREET, LAGOS




## Awon Iko ile wa lo f'oju kan oba

LONDON. Ninu ipade ominira ti awọn aṣiwaju wa lọ ṣe nilu Oyinbo, Sẹkiteri agba ti ilu Oyinbo Lennox Boyd ti o nṣe Alaga fun ipade ominira na, sọ wipe, alejì ko le wọ ilu ki onilẹ maṣe mo, on yio mu awọn enia diẹ ninu awọn ikọ wọnyi lati lọ ki Ajiyeluwa ọba Gẹsi, Elizabeth Keji on yio si jihin ohun ti awọn ba wa nilu Oyinbo.

A ri gbọ wipe, awọn enia mẹtadilogun lo ni anfani lati lọ f'oju kan ọba Gẹsi na. Diẹ ti a le daruko ninu awọn ti o lọ f'oju ri ọba ni, Oloye Awolọwọ, Sardauna Sokoto, ati Nnamdi Azikiwe.

Pẹlu aṣiwaju mẹta wọnyi, ni Gomina agba Sir James Robertson, Sir Alan Lennox Boyd, ati diẹ ninu awọn Minister ilẹ wa, gbogbo wọn yio jẹ mẹtadilogun ati awọn oyinbo jankan-jankan.

Lẹhin ti ọba ba joko tan, ni Sẹkiteri agba yio wa fi awọn ikọ gbogbo han ọba. Ọba na yio si gba wọn niyanju, nwọn o fi ọrọ wẹ ọrọ ni waju rẹ, yio sọrẹ fun wọn. Lẹhin na, nwọn a tuka.

---

## Isimi Odun Ileya ati Ojo Ibi Anobi

Ijoba ni ki a so ikede yi fun gbogbo awon to ngbe ile Nigeria wipe Gomina agba ti palase wipe ki ojo Monday 8th osu July ati Atalata 9th osu July je ojo isimi fun odun Ileya ti o mbo yi. Lehinna ki ojo 7th osu October 1957 je ojo isimi fun ojo ibi Anobi Muhamed (Maoludun Nabiyi tabi Nobiyu lawani)




# Ọwọn egbe W.H.O. Fe Pana Arun Ete Ni Afrika

W.H.O. Awọn ẹgbẹ kan ti a npe ni ẹgbẹ ilera gbogbo agbaiye (World Health Organisation) agbe ara di lati gbogun ti arun etẹ ni awọn ilẹ nla nla ti o mbẹ ni Afrika, ni awọn l'u bi apa ọna Brazzavile, apa ilẹ Kamerun, ilẹ Gambia, ilẹ Ghana, ilẹ Nigeria ati nilẹ Uganda.

Nwọn ni aniyan pe ni gbogbo ibiti awọn gbe darukọ nwọnyi, awọn ori to Iwọn ọgọrun ọkẹ enia to je adẹtẹ, nitoripe owo ti awọn alanu enia kakiri agbaiye ti dajọ le ni ogọrun ọkẹ dọla owo na si wa lọwọ awọn ẹgbẹ kan ti a npe ni (UNICEF).

Idi rẹ ti nwọn ṣe lẹ mura si akan yi ni wipe ki arun na le tan patapata lara enia, ti ko ni maran kakiri mọ, ki o maṣe si wipe a nṣa fun ara wa mọ tabi wipe a nya awọn apakan enia sọtọ mọ. O si daju wipe eyi ti a wiyi jẹ akan ti yio ṣẹṣẹ, niwọn iba ọṣu diẹ lagbara orişi egbogi meji kan ti awọn awujọ onişegun ṣẹṣẹ gbe de. Abulfones ati Domicitiary.

Ohun ti o fa sababi ni pataki ni wipe ki o maṣe si wipe awọn apakan enia nronu wipe, awọn ko ni anfani lati ma ṣere papọ gẹgẹbi awọn ti a bi wọn bi ki nwọn si mu ironu kuro lọkan wọn.

# Aramu Adajo Farakor'n

A gbọ irohin wipe, awọn ẹgbẹ Ọsọlẹ kan mura gẹgẹbi ijoye, awọn nla ilu, awọn si nje, nwọn lọ si abule kan, nigbati awọn de ibẹ nwọn bere Balẹ, nwọn sọ fun pe lati Abẹokuta ni awọn ti wa lati ma de ẹjọ nila na. Nigbati Balẹ ri wọn pẹlu ilẹkẹ lọrun, ọpa ẹdan lọwọ wọn, ati akẹtẹ Ogboni lori wọn o fi wọn wọ inu ile kan.

Bayi ni awọn wa ni abule na, nwọn nda ẹjọ, nwọn si ngba owo ni apo ara wọn. Sugbọn nigbati Balẹ abule na, ti o jẹ Agbapa njẹ Awo Ogboni lọ si Ilodi ni Abẹokuta ibẹ ni akara ti tu sepo.

Nwọn ran awọn ọlọpa wa lati Abẹokuta pẹlu mamugari, awọn ko awọn Oramu-kandu adajọ na, awọn ba wọn ṣe ẹjọ aiyederu, nwọn si ju ẹnikọkan ninu awọn adajọ na si ẹwọn ọṣu mẹsanmẹsan. Oramu ko şiwere kewu lo b'ori rẹ jẹ, ka mu torọ, ka mu torọ, ka fi sisi kun, ṣe wo di naira.

# Afoju Kan Riran Ni Kaduna

KADUNA Ni Kaduna nibiti oniwerohin wa lẹ ni aipẹ yi ni a gbọ wipe afọju awusa kan ti o ti ilu ọba awọn onihoko Kagoro leti Jos wa ṣe agbe ni Kaduna di ẹniti o ri iran.

Ọrọ na lọ bayi wipe afoju yi kuro ailu ti a npe ni Kagoro tan pẹlu ọmọ ọmọ kekere ti o nmu mọ ọna. Iye ti o di mọra ninu akisa aṣọ rẹ jẹ pọun mẹtẹla. Ko pẹ ti o gunlẹ si Kaduna ni awọn ọmọ jaguda ti yọ owo yi. Afọju yi wa bẹrẹ si damu, O sọ ẹkun wayi-wayi.

Obinrin kan ti o nta ẹso igi Mongoro wa ri idamu rẹ o fun ni meji pe ki o jẹ.

Bi afọju yi ti jẹ tan ti o nfi owọ nu omi oju rẹ ni o ba di pe oju rẹ la o si di ẹniti o nriran. O lọ ibosi gbo o l gbogbo enia si pe bo lori nibiti o gbe nfi ogo fun Ọlọrun.

# Ọlọla S. L. EDU

Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni S. L. Edu ti o koko se asoju fun ilu Epe ninu igbimo Agofin ni Ibadan, o si je onisowo. On lo se asoju ile Nigeria lo si ipade gbogbo-gbo kan ti awon egbe Commonwealth and British Empire Chamber of Commerce se nilu London,

Ogbeni Edu so wipe, on, gegebi asoju ile Nigeria, on yin awon ti o koko wa da ile ifowopamọsi ti Barclays Bank (D.C.O.) silẹ, bakanna ni on tun yin awọn enia ti o tẹle ipaṣẹ awọn ti o kọkọ da iṣẹ na silẹ, ti nwọn si duro dara-dara, lori eyiti ilẹ Nigeria fi ṣẹ le duro gbọnin de aye ti ilẹ na fi nilati di ọkan ninu awọn ilẹ ọjọgbọn ni gbogbo agbaiye.



Barcklays Bank ati awọn Banki miran lo ṣe iranlọwọ lati abo wa ga de aye na. Mo ni igboiya lati sọ wipe nigbati o ba di igba kan Barklays Bank ati ilẹ Nigeria yio di ọtẹ pọ, awọn o si ma ṣiṣẹ papọ fun ire ilẹ enia dudu (Nigeria)

OBERE RE, S.L. EDU

# Pakilaso pa Akinlaja

Lati owo EYO

Nigbati ile Ijoye m b e ni ija ye okunrin jagunjagun kan wa nigbani ti awon npe ni Akinlaja, o ni owo, o si te ni ogun. Ko si ohun kan ti o nda lamu rara, sugbon ese ni ori re ma nyi nigba kokan. Nigbati ori re ba yi tan, gbogi re yio gunu lolu tore ti yio gbe owo oogun re wo yio si l o joko ti iri to ba ni Oro ninu lorun, n si ma p e Oro igi na wipe bi o ba to ki o jade wa, ki awon jijo le.

Bayi ni Akinlaja ma nse. Bi o ba wo ewu oonun re, akoko yio ma ko, ewure yio mike, iwo yio ma e gbohun onigara laifoju kan gikan iwo yio ma duro ilu gangan bi o ti wipe, awon olu ilu tele lehin, iwo yio si tun ma gbe enjiti o n p e o l o. Eyato tani oorde Elinla, elis yio ma jade n i igbani re, ni eyi re ati eruko nla, nigbati o ba rin lo, ti ma jade ni ese re.

Ewe, n korita ona Ijaiye Esu kan wa nibe ti o je wipe, ko si onpe ti a fi akara ru. Awon Arokin so wipe Oya Sango lo le ese Odara na ni be. Ko si si Irunmole kan ti o le ko Esu na lolu. A tilegbo wipe Esu na a ma nse odiosi rara ti awon Egun ti ni lati fi ori lo onin igbe woliu sugbon ki Esu na ti buru to yi, ko ti bawa ndara si Akinlaja ri.

O daju ojo kan ti nkan Akinlaja ko si lori, o ru idi igi, ikin, oko, o gbe ona ooyan re wo, o kori si irdere ni bati Pakilaso wa. (Oruko ti n) awon epe nso na. O bere si kole na ala, Esu yi, awon o ti o akoja lo koja bo ma inbiu fo ba Are wipe, Akinlaja ma n k o l e ti Pakilaso lulu.

Are raise pe e Akinlaja ti di un, bi on ba ten ri enikan wa ni ibile tabi ti o koja ni nin on yio jeki awon re iona ka. Are si mo e, bi o ti wi si, ni yio se. Laifa oro gun, Akinlaja pari ise ti o nko Akinlaja papan mo i r u mojo ti Pakilaso je. Nitorion eiabe ti n pari ile kiko na tan, o tun nada lo gba apo oogun re yoku konun o si lo joko ti esu yi lorun, nireti wipe nigbati o ba ga yio se i a d e nigbana awon yio fi peki ko peki gegebi o ti m a nse fun awon O r o igi gbogbo.

Lati ori ale ti o ti k o sinu ile na Pakilaso ko fi ara han a, lati iwon abopo mejr ale lo ti gegan sile de Esu na nigbati e to iwon agogo marun owuro, beni orun kua Akinlaja bi o ti olorugbe beni Pakilaso yo si ti si be lori o si gbe ori re lo kale sibi ojubo re Akotakiji ni fun gbogbo enia o bi ti ori Akinlaja ni bali Esu gbe gbe fi kale si asubuleho ni. Nigbati ile mo irohin ti ebojikan kakiri ilu Ijaiye wipe Pakilaso pa A k i n l a j a. Awon elemitan ti o mo Akinlaja nigba aiye r e, ko gbagbo wipe ire ohun he le sele si i rara sugbon nigbati awon ri ati re ni biti awon fi palesi, sabako! o di agubulebu.

Lasiko na ni awon olorere ile, awon serekode ilu ati awon ogere ilu wa tere si fi o r o Akinlaja je ilu nsogun kakiri ilu bayi wipe:-

Pakilaso pa 'Kilaja je
Pakilaso pa 'Kilaja je
E w'ono Imade e wonu ede
E w'enu Akilaja bi o se.

## Owo olopa ba awon Eniakenia

KANO Enia merinlelogorin ni awon olopa ramu ninu ile onje kan ti o wa ni Sabongeri Kano fun esun ibi kurin ati ifi ri iranu. Awon enia na ko ti Sakan se ile, awon nrienbene yo kori ri.

Nwon n s a iduro fun awon enia die ninu won, sugbon awon nsgindilogoji ninu won lo yi omo osole si olopa ko lati gba iduro fun won.

Eyi ni akoko igba ti olopa gbogun lo ka awon omo jaudu na mo ile onje ni Kano.

## Igbimo Ipade Sinodu Kuna

Olota

Jowo gbami laye die lati so si oro ti awon Onigbagbo Kiriyo se ipade lori wipe bi Onigbagbo ba nse odun, won ko gbodo fun awon Imale ni nkan, tabi ki awon na gba nkan lowo Imale.

Emi ti mo nsoro yi ojalowo Onigbagbo ni mi. Sugbon mi ko gbagbo enia mo wipe awon Onigbagbo ti so iru oro yen, awon na mo wipe "aba ti ko le se ni oro na". Bo tile nse ni gbogbo ilu kise bi iru ilu Eko yi; Ni bi to je pe, lati odun gboro ni ati ari omo Kiriyo ati Omo Imale ti won n s e egbe kan na po, ti ko si si ija larin won, ko wa je pe iru ofin ti ko fara han ninu Bibeli tabi Kurani ni yio wa so ore di ota.

Nje iru re le se ?

Mo si tun fe ki awon okawe te nkan sinu iwe yi mo wipe kise ofin ti ti gbogbo awon Onigbagbo ni eyi. Nitoripe orisirisi Kiriyo l o w a. Bi C.M.S. ti mbe, beni Aladura mbe, b e n i Roman Catholic m b e, e.t.c. Sugbon oruko Igbagbo kan na lo ko gbogbo won po. O si ye k'ale mo iru awon to nse iru ofin bawonni.

Bi emi ti je Onigbagbo yi mo ni Lemomu ni ore, o nisan ofile mi, emi na si n j e ile r e, sugbon gbogbo nkan to ba lo nipa iborisa, emi ko si ni be o.

Abo mi re o.

Emi ni,

E.A. Adekeye



# Ipade igbimo ilu Oyinbo ti 1953



Aworan ti a nwo yi ni ipade igbimo Ofin titun ni ilu Oyinbo eyiti nwon se ni odun 1953. Awon asoju ijoba Iwo-Orun lo joko ni okokan ti o koju siwa, awon asoju ijoba ile Hausa lo joko ti nwon ko ehin si wa, awon asoju ijoba Ila-orun lo joko lowo osi.

Oloye Awolowo lo wo agbada funfun ti o si de fila Awo, ti o duro ti o nsoro Alhadi Ahamadu, Sardauna Sokoto lo ko ehin siwa pelu lawani lori re. Ogbeni Azikiwe lo wo aso oloyinbo ti o si joko lowo osi.

Adura wa ni pe ki ipade ti nwon lo l'odun yi dun bi oyin, ki eti wa si gbo ire nibe.

## Ikilo igbehin

Obinrin kan ti o ti mbẹ ninu aisera, nigbati o bẹrẹ si ri ofere ọrun, pe ọmọ rẹ sọdọ o si bẹrẹ si wipe:-

Ọmọ mi, nigbati akoko ba to fun ẹlẹda lati pa oju mi de kuro ninu ogo ti aiye yi, mo bẹ ọ, maṣe ko ẹgbẹ-kẹgbẹ, maṣe rin irin iranu, nitoripe, ẹgbẹ buburu a ma ba iwa rere enia jẹ.

Maṣe fi ọwọ le ohun kohun ti kọ nṣe tirẹ, maṣe ṣagbere, koju si iṣẹ rẹ.

Nigba kigba ti o ba fẹ lati ṣe 'ranti mi, nko wa ebọ tabi sara lati ọdọ rẹ. Ibe ohun ti mo nfẹ ki o ṣe fun mi ni wipe, ki o darıji ọta rẹ, kio si ba dọrẹ, hẹni ki o ma yonu si gbogbo awọn ti ko fẹ ọ, ni ṣiṣe bayi ara yio rọ mi ni isa oku.

## Rogbodiyan tun be ni Nikosia

NIKOSIA. Ni ọsẹ kan sẹhin ni Nikosia, ni biti ijọgbọn asaba ma hẹ silẹ nigba gbogbo, ijọba Gesi kede isẹde, nitori ki alafia le wa.

Sibẹ sibẹ, ija gboro tun bẹ silẹ larin awọn ara ilu na ati awọn Ọlọpa. Ohun ti a si gbọ pe o da ija na silẹ ni wipe, lakoko ti rogbodiyan ija gboro ṣi gbojikan ni ilu na, larin ijọba ati awọn ara ilu yi, Aṣiwaju awọn janduku ti o mba ijọba fi ori gba ọzi, ti nwọn npe ni Gregoris Afcention ku ninu ija na.

Ọkunrin ti o ku yi ni awọn ara ilu na sọ fun ijọba wipe, awọn fẹ ṣe isin fun iranti oku aṣiwaju wọn na, ti o di ero ọrun, ijọba tako wipe, awọn ko gbọdọ danwo, nitoripe akoko isẹde ni awọn wa. Ṣugbọn awọn enia na fi dandan le wipe awọn ko gbọdọgbe tijọ ba dari, awọn ṣa fẹ ṣe aṣa ilu wọn ni. Eyi ni ohun ti o da ija nirau silẹ.

**FEMITONE**

Je EGBOGI ATATA ati ATEJESE fun awon ABOYUN ati ABIYAMO

4s 6d

AN'ORIN CHEMISTS Ltd. 116, King George Avenue, Yaba ati awon ẹka rẹ. Phone 44288

**L. E. D. B.**

**Eto Titun Arin Ilu Eko Se**

**Akiyesi fun awon onile**

A fi eyi ṣe ikede fun gbogbo enia pe nipa ofin ti a ṣe ninu igbimọ eto titun arin ilu Eko ṣe Apa ibiti a pe ni agbegbe karun (Sub Area 5) yio bọ sọwọ igbimọ L.E.D.B. lati ọjọ kini oṣu June 1957.

2. Agbegbe karun na (Sub area 5) gẹgẹbi a ti ya sinu iwe ifiban No. L.T.P. 840 ti o wa fun ẹnikẹni lati ṣe ayẹwo rẹ nile iṣẹ wa ni Reclamation Road tabi nile iṣẹ wa ni Broad Street ni Eko, wa fun awọn agbegbe nwọnyi:- Palm Church Street, Victoria Street, Breadfruit Street, Martins Street

Reclamation Road, Lagos.

J. W. Henderson
Chief Executive Officer.



Bi o ba nsise ninu ojo fi egbogi yi pa gbogbo irora asiko ojo

ELECTRIC Balm



# Ojo Ariya awon Jagunjagun ni Zaria

(Lati ọwọ ỌLA ONATADE)

Oyinbo ni ijo ti on ti d'aiye tangan-tangan ki aiba lọ ni ọwọ on. Beni ọrọ awon ologun ti Gẹsi ri. O bere lowo oga ogun kan ti a npe ni Nelsini (Nelson) nigbati o ko awon ọmọ ogun lọ ṣe atipo ogun nla kan ti a npe ni Ija Woteluu (the Battle of Waterloo), ọrọ Ọsun ua kamọjọ.

O so a ko, o si fese ọgbẹni kọ. Ọta ibọn nke bi tere, egunlọgọ enia nsubu lọ ni ọtun ati osi Ọta'gun Faranse ti wọn nta ju ni t'on si o ni lati leke. A wi-a enibo, ọta ba Olori-ogun Nelsini. Bi o ti nj'apọro iku ti awọn ọmọ ogun re ndu emi re, Ọgagun Nelsini wa fi ohun sile npa ọrọ ikẹhin ti o sọ bayi :- "Modupe mo ti ṣe iṣẹ ti Olorun ran mi"

Ni aiye ti bẹẹkẹ ma de Oke Ọya nibiti a gbe nṣe iṣe ikọ ti a wo ti nja ogun, ojo ti wipe ki enia di amure giri ti o ma je ki ọm ko on nile ki iṣe ẹṣẹ.

Bi awọn ara ilu Naijiria ba ni ki awọn ọmọ ogun ma lọ ko bi a ti doju ija kọia, ki o ma le ṣe ni jamba, ki iṣe ẹṣẹ, nitoripe lati wọn ko lo ko bere.

Mo fẹ ki o tele mi nisisiyi lọ si Kaduna ati Saria (Zaria) ki o lọ wo okan ti Ijọba nṣe fun awọn jagunjagun ti wọn ma tọju wa loju.

Jowo, eko ba e so wipe ni ọla ọjọ rere, ogun a bẹ sile, bi orin kan ti awọn ara Eko ko ni wọn nkọ ni ọgọji ọdun sẹhin:-

"Eko lagbagbọ o wọn l'ọ a paron,
B'aye ba paron K'ajọ mọ lọ,
Bi ko ti paron K'ajọ gbe bẹ,
Won Ibadan wa puro kan l'Eko."

Ni Naijiria, ilu Saria (Zaria) je ilu ti a ma ako awọn omọkunrin lọna ti a ti ṣe nja ogun l'ọrọ ati ni ilu Kekere ni ọjọ ti a ti ni lati ohun wa. Eyiti a n ti Ijọba ṣe ti ilewe awọn jagunjagun na ni ọna ijọba ati a lọ, o wa kamọmọ.

Kaduna ni a ko de ọjọ ti elekewe ni, ti a ti awọn aṣẹmọṣe ọdọ Olofin ti a npe ni Posi Bataliọni (ọmọ Ogun Oba nilu Nijiria). Wọn ki iṣe eyiti a nfi ọmọ rọ sehin nibu eto ija. Awọn wọn ki ponpon ese won tun wa ropo bi ogun ile Oba Farao.

Ko nṣe iro ki wọn lo gba e siru iṣe ọgun Dokita ni lati ripe ara re da ṣakaṣaka. Ona meji lo wa ṣi sile ti o le fi gba wọle ikini ninu ko je ọmọ ilewe ti ede Oyel re ti kọja" a de go, a de kom" (com") awọn yen ni a npe ni Boyi Kompiani (Boys' Company) ti wọn kọ lati di oga lehin ọla Oṣ'o' ọmọde ọlọdun merindinlogun de meṣdilogun ni won nfẹ, wọn ko fẹ arugbo bi temi.

Awọn iru enia keji ti wọn tun nfẹ lati gba sinu iṣẹ yii ni awọn agunlasọlu enia ti wọn si mọ iwe Oyinbo ko ti wọn si tun mọke diẹdiẹ.

(Koko yari)

# Ija ilu Algeria Di Ijogbon

Algeria. Gegebi opolopo enia ti mo, ote ijaghoro to sele nilu Moroko lo gberan titi de Tunis on kanna lo de Casablanca) on kanna lo si ri wonriwon.

Nilu Moroko, nibiti ija na ti sele, rogbodiyan ko le to ti ilu Algeria nibiti ija na gbe ya yoboke. A gbo wipe awọn ara ilu Algier ni itaju ju awọn ile Larubawa apa Iwo-orun ile Afrika yoku lo.

Nisisiyi ija na ti wa kuro ni ijaghoro larin awọn Algeria ati ijọba Faranse, o wa di ogun jija gbogan, ti opolo Faranse wọn ti bere si nipa ẹmi ọmọ enia larin won. Ohun pataki ti o ndun awọn Algeria ti nwọn nfe gba lowo ijọba Faranse a ko mọ.

Ogun ti awọn ijọba mejeji pade ja lapa yi enia marundilọgọrun ni ẹmi re nu awọn Soja Faranse medogun lo ku ninu ogun na.

Lowo ogun ati ote, ohun rere gbo 'ra.

# Awolowo gba obi nilu Oyinbo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Awolọwọ nigbati o sọkalẹ nilu Oyinbo ohun ti awọn rope o yẹ o si to ki nwọn fi yẹ alejo si ni obi.

Obi na ni a nwo yi ti Omidan Joke Ogunmokun enitì o lọ kọ iṣẹ gẹgẹbi a ti nṣe itọju alaisan ati olokunrun nilu Oyinbo ngbe fun yi.

Eniti a nwo lowo ọtun Awolowo ni Oloye Okorodudu, nse ni gbogbo awọn Oyinbo ati enia dudu ti o wa pade wọn lọna ati wọn ṣe fran wo.


## Ogun Aran (Ejo Inu)

Aradan Worm Expeller ni ogun aran pataki fun omode ati agba okunrin ati obinrin. Ko igo kan lati ya gbogbo awọn aran buburu ti o nba ọ ja nino danu. Bi o ti npa aran, beni o npa 'yin wọn. Wa ra tire ki o lo loni. Igo kan je 2/6d. Owo-Oko si je 1/-

THE EGB. TRADING ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.





Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23370